**OBA ONI SE ODUN KOKANLELOGUN LORI OYE**

# IROHIN YORUBA

Ede Oro Wa— "IWAJU L'OPA ẸBITI NRE SI"

**Akiyesi !**

Ti ẹ ba nkọwe si wa ki ẹ ma a kọ ọ yanju, ki a le tete ma a tẹ ẹ jade fun nyin, eyiti ko ba yanju dele kole jade rara. Nitorina a tun tẹ ẹ mọ nyin leti daradara "Ẹ ma a kọ iwe nyin yanju o"

Olotu

IGBAKEJI ALAGA APERAN D'ENI ORUN ; AWỌN OLORI ALUFA IMALE SE IPADE

VOL. IV No. 682 IBADAN, MONDAY, SEPTEMBER 10, 1951, OWO IWE IROHIN YORUBA — KỌBỌ KAN (1d)

## Ibanuje Dori Agba Kodo !



Eyi ni aworan awọn ikọ ti awọn ẹgbẹ N.C.N.C. ran lọ si ilu Oyinbo lati gba eto titun fun Ijọba Nigeria ninu ọdun 1947. Bi ẹ ti ri wọn yi ni nwọn' ṣe doriko-do pẹlu ibanujẹ ati itiju kuro lọdọ Ọgbẹni Arthur Creech Jones Alakoso Ijọba ilu amọna Gẹẹsi ( Secretary of State for the Colonies ) igbana. Ẹ wo alaye irin ajo wọn ni oju ewe keji iwe yi.

### BABA WA LADIPỌ ỌRUN RE O

OGBOMUSHỌ—Ni ọjọ keta oṣu kerin ọdun yi (3/4/51) ni baba wa Ọgbẹni Ladipọ ti ile Bankọle Oke Tara ṣe alaisi ni deede agogo mẹta ọsan. Ni ọjọ keje ti baba na ku ni nwọn ti tẹ waya si ọmọ rẹ Ọgbẹni Samuel Agboọla Ladipọ ni Bogoso, Gold Goast.

Nigbati o si de si ile ni nwọn ba bẹrẹ oku na ti si sin ni ọjọ kẹrindinlogun oṣu ọdun yi, ọmọ-loku na si pe gbogbo awọn mọlẹbi ati orisirisi ẹgbẹ si ibi inawo Isinku na. Ẹgbẹ Imọlẹ-Ntan l'ọkunrin ati l'obinrin ni o kọkọ wa si ibi oku na pẹlu Ẹgbẹ Atanda ọkunrin pẹlu ọpọlọpọ awọn Bọrọkini ati gbajumọ adugbo.

Ẹnu kọ irohin ni inawo awọn Ọmọ-oloku na fun orisirisi ẹgbẹ ti nwọn pe ati awọn enia pataki ti o wa si ibẹ, bi enia ti po to bẹni nwọn si fi ẹjẹ ati mimu tẹ gbogbo wọn lọrun.

Awọn diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn ogunlọgọ enia ati orisirisi ẹgbẹ na ni awọn Ọgbẹni Ọga Wolewole ati awọn ẹmẹwa rẹ. M O Ogunrẹmi, J Ladipọ, Joseph Gbami, James Arẹmu, Samuel Ajala, awọn Iya-afin Ajelgbe, Alaga Ẹgbẹ Imọle obinrin ati Adenikẹ (Alamojuto)

Ninu awọn Ijọ Isalẹ Afọn ti o wa sibẹ ni S A Ọdẹwọle, S Oguntọla, E O Balogun, Daniel Ayọọla, J A Awolọla, Salami Alagbe, E A Akande Amulekan- gbo ati awọn ti aye ko si fun lati da oruko wọn.

Awọn Ọmọ Ologbe na ni J L Ajani, Esther Lapade Ladipọ, S A Ladipọ, E L Ladipọ, E T Ladipọ, D O Ladipọ, E A Ajadi Ladipọ ati Iyafin Abiara A si ki awọn ọmọ-oloku na ati awọn Iyawo oku na pẹlu gbogbo awọn ọmọlẹbi pe nwọn ku inawo, nwọn ku aṣẹhinde, ki Oluwa jẹki ẹhin baba na o dara o, amin.

No. 372.

## The Pharmancy Ordinace
(Chapter 169).

The attention of the public is invited to the provisions of section 56 (1) of the Phamrmacy Odinance, which prohibits the puplication of advertisments relating to certain diseases.

The Public is hereby warned in its own interest that any publication of this nature constitutes an offence under the Ordinance.

## Ọba Ọni Se Ajodun

Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ keji oṣu yi ni a gbọ okiki ipalẹmọ ti gbogbo ilu Ifẹ ti bẹrẹ si rọ kuku keke ti ariwo ibọn gba ilu kan lati fi bẹrẹ ajọyọ ajodun kọkanlelogun ti Ọba Alaiyeluwa Adesọji Aderẹmi Kini Ọni Ifẹ ti gba ade.

Nigbati o si to deede agogo mọkanla ni awọn Igbimọ Ilu ti pese si Afin Ọba lati ṣe eto bi gbogbo ẹyẹ ti awọn fẹ ṣe na yio ti larinrin si nitọpe fun odidi ọsẹ kan ni awọn fe fi ṣe ajọyọ ajọdun na.

Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejọ oṣu yi ni nwọn fi ijo (dance) pari ajọyọ ajọdun na, nigbati o si di ọjọ keji ti iṣe ọjọ Aiku ati ọjọ kẹsan oṣu yi na ni Ọba na paapa pẹ'u awọn Ijoye rẹ ati awọn alabaṣẹyẹ na ni ilu ati lati ilu okere wa lọ ba Ọba na ṣe isin idupẹ pataki fun ti ajọyọ ajọdun na ni Ile Isin Saint Philip Aiyetoro.

Adura wa ni pe ki Ọlọrun fun Ọba na ni ẹmi gigun ati alafia ara lati le fi ṣe iru ọpọlọpọ ajọyọ ajọdun igbado bayi. Ade a pẹ lori bata a pẹ lẹsẹ Ọba o. Kabiyesi !

## Ọgbeni Salami Ladotun Ku

IBADAN—Ọgbẹni Salami Ladọtun, Igbakeji Alaga gbogbo Ẹgbẹ Alapata, Eko, ṣalaisi ni ilu Ibadan ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi.

Gbogbo awọn Alapata ti Eko ati Ebute Metta ati Baba Ẹgbẹ awọn Ọgbẹni Oṣelu A. Y. Ojikutu lọ pẹlu awọn ti o ṣe isinku na ni Ibadan ni ọjọ keji ti o ku . Nwọn ko ta ẹran ni ilu Eko ati Ebute Metta lọjọ isinku na,

## Awon Olori Imale Se Ipade

ỌYỌ—Igbimọ Olori awọn Alufa Musulumi (Chief Imams) ṣe ipade nla ni ilu Ọyọ lẹnulọlọ yi. Ọba Ọyọ, Alafin Alaiyeluwa Adeniran Adeyemi Keji C.M.G. lo ṣe alaga lọjọ na. Nwọn sib ṣe ipinnu pe ọdun Ileya (Eid-El-Kair) yio jẹ ṣiṣe ni ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi,

Ẹgbẹ Muslim Congress ti Nigeria eyi ti Alafin na jẹ ọkan ninu alatilẹhin nwọn (Vice Patron) lo pe ipade na.

E Dibo Fun
Ẹgbẹ Afenifere
Action Group

OWE:- AIFẸ'NI PẸNI AIF'ENIA PENIA TI ARA OKO FI SAN BANTẸ WỌLU

No. 374.

# NOTICE

## Loss Of Receipt Forms

It is hereby notified that the undermentioned unused receipt forms have been reported lost from the office of the Medical Officer in/Charge Massey Street Dispensary, Lagos.

These receipt forms are hereby cancelled. Any receipts purporting to be issued on such forms are unauthorized and give to the person to whom they may be issued no rights, nor can they be accepted as evidence of the discharge of any liability.

Any person who comes into possession of any of the undermentioned forms or is able to furnish any information relating to them should report the facts to the nearest police station.

Particulars of forms :—

Treasury Receipts Nos. A. 134451 — 134500

E C G FULLER
Ag: ACCOUNTANT-GENERAL

No. 372.

# NCTICE

## LOSS OF RECEIPT FORMS

It is hereby notified that the undermentioned unused receipt forms have been reported lost from the office of the AGRICULTURAL SUPERINTENDENT DAUDAWA.

These receipt forms are hereby cancelled. Any receipts purporting to be issued on such forms are unauthorized and give to the person to whom they may be issued no rights, nor can they be accepted as evidence of the discharge of any liability.

Any person who comes into possession of any of the undermentioned forms or is able to furnish any information relating to them should report the facts to the nearest police station.

Particulars of forms:-

Receipts Nos. C869799 and C869800
From Treasury Receipt Book 6

E. C. G. FULLER
AG: ACCOUNTANT--GENERAL


# O Nwo Iko San L'ogan !



Bi idan ni VENO'S COUGH MIXTURE yi ma a wo ikọ san, a si tun ma a ko gbogbo idọti ti i ma a dun enia ni ọna-ọfun, ni aiya ati ni ẹdọ kuro. O si ti han si gbogbo aiye pe ogun iwosan ti ki i ba a ti ni fun orişirişi ikọ siya didun ati otutu ( Coughs, Golds, Bronchitis, Catarrh, Catarrhal Asthma, Night Coughs, Children's Coughs).

Kọ tete ra igo kan, dan an wo na !

VENO'S LIGHTNING COUGH MIXTURE

# VEHICLES FOR SALE

1,000 4x4 Fordsons and Chevrolets, Ex W.D low mileage and in first class condition. Painted any colour. Prompt delivery.
C.I.F prices on request

The Colnbrook Trading Co., Ltd.,
poyle Road, Colnbrook, Bucks. ENGLAND.
Cable: COLTRA SLOUGH



ABIYAMỌ ETI RE MELO!

Abiku ọmọ nda ọ l'amu bi ?
Awọn arun wọnyi ha nyọ ọmọ rẹ lẹnu bi !

AIPERI
ỌRẸRẸ
INU-IWỌ
OSI
IGBONA
IKỌ
IGBẸ-ỌRIN
OTUTU
IBA
JẸDIJẸDI

ati orişirişi awọn arun miran ti ima yọ ọmọde l'ẹnu ni igba EHIN HIHU. Lọ ra 'YARO' awo igba arun ọmọde ni fun gbogbo awọn arun ti ima yọ ọmọde l'ẹnu.

"YARO" ko pe meji ni gbogbo ilẹ Nigeria.

Ki iwọ ki o ri I pe orukọ 'YARO' ni o wa lara Igo na ki a ma ba ta adamọdi egbogi miran fun

# J. A. Ajao & Brothers

GENERAL MERCHANTS
10, Egerton Road, Lagos, Nigeria

A nta awọn nkan wọnyi— Işana orişirişi ( Matches ), Oogun Iyagbẹ, (Epsom Salt ), Kafura Pẹlẹbẹ ( Camphor ), Atike ( Face Powder ), Ọti Didun ( Mineral Water), Cement, Bata Funfun ( White Canvas Shoes) Leather Shoes ( orişirişi ), Beer, Shnapps. Gin, Wine, Brandy.

## Medicine Stores

A tun nta awọn orişirişi ògun Ịni oke Şọbu wa — Oogun Naruu Iba, Atun-ẹjẹ-şe, Ikọ, Jẹdi-jẹdi, ati ògun fun Obinrin ati Ọkunrin Lakuregbe, Ehin Ọmọde.

# Abiyamo! "Bamwo" De!! Alajela Omode!!!




Idẹra ati alafia de ! Ko si ibanujẹ ati aisun mọ. Angẹli olutọju ọmọ rẹ ti mu ẹbun kan wa fun u lati ọrun wa "BAMWO" ni orukọ ẹbun na. O dara pupọ fun Inu-iwọ, Iso tabi Igufẹ, Iba, Igbona, Eyi, Ailesun, Ibinu-sodi ati orişirişi aisan miran ti o ma nşe ọmọde lakoko ehin hihu. Dan Igo kan wo, iwọ yio si ri pe o dara ju eyikeyi ninu awọn ogun ti o ti nlo fun ọmọ rẹ lọ. Igo kekere 2s. 6d igo nla 4s. 6d. ọkọ 1/-.

# The Egba Trading Aradan Stores.

144, Denton Street, 18 Denton Bridge Street, P. O. Box 2, Ebute-Metta. Phone 569. A tun wa ni New Motor Park Ogunpa Ibadan.

